# IROHIN IMOLE

IMOLE AIYE, ORE T'ENI GBOGBO LAWA

No. 708 MONDAY JUNE 1, 1964 (2D)


## ARE AGOGORO EYO KU OJO MEFA

EKO:- Ni deede agogo mejo ale ana ojo Aiku ti ise ojo kokanlelogbon osu ti o koja yi ni irohin kan wa ninu ile ise wa pe, ni ojo Abameta ti ise ojo kefa osu yi, ni nwon o se are agogoro eyo yika kiri gbogbo ilu Eko

Onirohin wa kan tawalolobo pe, Oloogbe, Olola Coker, ti ise baba Oloye I. B. A. Coker, okan ninu awon adajo agba ni ilu Eko ni nwon fe se are eyo na fun

Onirohin wa fi ye wa pe awon alase are eyo Eko ti bere si mura sile Nwon si npa le mo fun ere Eyo na eyiti nwon yi" se ni ojo mefa loni.

Awon alase na tise opolopo alaye lo ri bi awon ere Eyo na yi ti se lo ni ojo na Nitori idi eyi oni we Irohin wa Ejongboro ti lo si odo awon alase ti nwon nse eto ere Eyo na.

Nitorina gbogbo enyin ti e ba fe lati mo bi eto ere eyo ti nwon fe se na ti ise nlo, ki e maa ka iwe wa ni ojojumo, ki nwon le mo ohun ti nwon fe ki awon ara ilu o se ni ojo na, ati bi eto na ti se nlo ni abele. Oniwe irohin wa Ejongboro yio maa so gbogbo re fun nyin ninu iwe wa ,, Agogoro eyo, we maa jagbon die, huhu- ha- haa-! ".

# AWON OSISE BA OLOPA FAGA-GBAGA!

IDDO :- Oro di peentuka, nigbati awon Osise se ipade nla kan ni Yaba ti gbogbo won si se ipinnu pe awon lodi si iwa ti Apapo Ijoba Najiria hu lori abayori Igbimo Oluwadi ekunwo owo osu awon osise ti gbogbo won si nto bowa si Eko ti awon Olopa yo si won pelu Olugbongbo ti gbogbo won si tuka yanga ni ojo Abameta ti ise ogbonjo osu ti o koja yi.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awon asiwaju Igbimo egbe awon osise ni nwon lo ba awon omo egbe won soro lori ekunwo owo osu ninu ile oti kan ti nwon npe ni "Majestic Hotel, Yaba."

Nigbati nwon pari, oro na, gbogbo won pinnu pe, awon ko faramo iwa ti Apapo Ijoba hu lori oro na, nitoripe, Ijoba ko so ipinnu won, bi nwon faramo ohun ti Igbimo na wi tabi nwon ko faramo.

Awon osise na tun so siwaju pe, gbogbo ileri ati ipinnu ti Apapo Ijoba tun se fun awon ni nwon ti kuna lati muse lori oran ekunwo osu awon osise, eyiti Olola Morgan se.

Nwon tun se alaye ninu ipade na pe, lati ojo ti awon Oluwadi ba ti se iwadi ekunwo osu awon osise pelu ipinnu Ijoba ni yio jijo jade papo, sugbon eyi ti o jade yi ko si ribe rara.

Nigbati awon ri oro na bayi, awon lo si odo Ijoba nwon so pe ki awon lo se suru di Ose meji. Nwon ni ose meji pari nwon tun ni ki awon lo se suru Ose meji sii.

Nigbati awon Asiwaju egbe osise jabo ise won fun awon osise, awon kosi so pe awon ko faramo ohun ti Apapo Ijoba se lori oro na awon si fe fi ilodi awon han. Nitoripe B. a aba yo ipin loju ti a ko ba fi han

## Ponpo Olopa Lara Awon Osise! Hen !! Emi O Le Gba !!!



Aworan Oke yi ni ti awon Olopa ti nwon fi ponpo dara si awon osise lara

oju, oju ko ni mo wipe on nse obun

Awon enia na ni ti o ba tun di ose meji, Apapo Ijoba le tun so pe ki awon tun lo mu suru ose meji miran.

Nikehin, gbogbo won gba pe o ye ki awon to lati Yaba lo si Eko, ki awon fi edun okan awon han awon alase Ijoba lori oran na, ki won o le mo je, oro na ndun awon, ati bi nwon ti se nre awon je.

Lesekese ni gbogbo won ba to si oju ona ti nwon si gbe Ogbeni Michael Imodu si ejikan titi ti nwon fi de Iddo.

Nigbati awon enia na to de Iddo, gbogbo awon moto ni ko ri aye koja-mo loju ona, ti awon moto si to lati Iddo titi de Yaba ti nwon ko ri aye koja loju ona.

Bi nwon ti nlo ni nwon nkorin owe, sugbon bi nwon ti nbe sotun, bosi Osi ti nwon nja ewe odan, ni awon Olopa ba yo si won lojiji ati lairotele, ti nwon si ngna won ni ponpo bi ejo aije.

Lesekese ni oro ba di bo o lo o ya mi ti gbogbo won si tuka yange, sugbon awon Olopa se Olori Igbimo egbe awon osise meji lese, lesekese ni nwo si gbe awon meji lo si Ile-iwosan.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa pe, awon Asiwaju Igbimo egbe awon osise meji na ni, Michael Imoudu ati Alhaji Adebola.

Onirohin wa fi ye wa pe, gbogbo ewu agbada funfun ti Alhaji Adebola wo lo kun fun eje, nigbati nwon o fi gbe de Ile-iwosan.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, awon osise ti se ipinnu pe, ti awon ba lo si ibi ise ni owuro yi, awon ko ni fi owo kan nkankan, gbogbo awon ni awon yio joko kale ti awon ko ni sise.

Siwaju eyi ni awon Asiwaju egbe osise ti lo ri Oloye J. M. Johnson, Minista Alamojuto eto ise ati ti alafia ilu, osi se ileri, fun won pe, ipinnu Ijoba yio jade ni otunla ti ise ojo keta osu yi, sugbon awon asiwaju egbe osise na kosi Minista na lenu.

Irohin fi ye wa pe Apapo Ijoba ti fi iwe abayori iwadi ekunwo osu na ranse si Ijoba kookan ni Ipinle, lati so eto won, sugbon Ijoba Ipinle Ariwa lodi si abayori Igbimo oluwadi na, nwon o si kowe si Apapo Ijoba ni ose yi.

Irohin fi ye wa pe kosi owolowo awon Ijoba Ipinle Ariwa lati san owo osu awon osise to iye ti Igbimo Morgan so ki won maa san; Nitori idi eyi, Apapo Ijoba ti pase pe ki awon osise ti nte iwe na, ki o da ise won duro na.

A gbo pe Ipinnu Apapo Ijoba ko ni le jade ni ojo ti Minista alamojuto eto ise da fun awon osise.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe, gbogbo awon osise ti fi aake kori pe awon ko ni sise loni, gbogbo won ni yio da ise sile.

Irohin fi ye wa pe, awon Olopa nwa Ogbeni Michael Imodu,kiri lowo bayi, nwon ko si ti ri i Awon osise ti kowe si Olola Nnamdi Azikiwe, Olori Apapo Ijoba Najiria ati Alahaji Abubakar Tafawa Balewa lori oro na.

Tiitidi asiko ti a nkowe yi, awon Olopa si nwa Ogbe ni Imodu, sugbon awon osise ti so pe awon ko ni sise loni, oniwe Irohin wa Ejongboro yio ma a lo yika gbogbo ile ise Ijoba ni owuro yi, yio si fun nyin ni ekunrere irohin nipa ohunti o ba sele kakiri ilu ni owuro, e o gbo won pelu aworan ninu iwe wa ni owuro ola,

# ỌRỌ OLOTU

## Ẹnyin Alakoso Ijọba, E Dakẹ Ni?

Ninu Iwe Irohin wa ti o kọja ni a ti ṣe irohin kan fun gbogbo ẹnyin onkawe wa pe, Dokita Okpara Alakoso I ọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ (N C N C) mbọ wa ṣe ibẹwo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣugbọn o fẹrẹ jẹ pe, irohin na kc ti jade tan, ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun fi ṣe ofin pe ko gbọdọ si ipade gbangba ode tabi iwọde yika gbogbo Ipinlẹ na.

Awọn baba wa a ma a pa ni owe wpe "Otitọ ọrọ ṣoro sọ, o si koro, ṣugbọn bi o ti wulẹ ki otitọ ọro koro to yio ṣe wa ni ọpọlọpọ anfani bi a ba le sọ ọ ti a si tun gba ọrọ na"

O jẹ ohun ti ko ba oju mu, ti o si koro lati gbọ si eti, pe nigbati Alakoso Ijọba Ipinlẹ kan nlọ ṣe ibẹwo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni Ipinlẹ kan ni Ijọba Ipinlẹ na ṣe ofin pe, "ko gbọdọ si ipade ode gbangba ati iwọde" jakejado Ipinlẹ na

Awa oniwe irohin Imọlẹ ti sọ ọrọ yi lẹẹkan, awọn Yoruba ni ti Alagbadẹ ba nlu irin timọtimọ ti ko da ọwọ duro, ki a mọ daju pe, ami wa nibẹ nitoripe, lati igbati awọn ti da ẹgbẹ Dẹmọ silẹ, ni a ti ngbọ lati ori ẹrọ-asọrọmagbesi pe, "ẹgbẹ ti nwa alafia, isọkan, ifaiyabalẹ idagbasoke fun gbogbo enia" ni ẹgbẹ na.

Owe kan sọ pe, "O rọrun lati sọ ju lati muṣẹ lọ" O jẹ iyalẹnu pe, gbogbo ihuwa si awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ yatọ patapata si ohunti awọn npe ara wọn fun awọn ara ilu.

Ọrọ mimọ Ọlọrun tun sọ fun wa pe, "Ifẹ a ma a mu suuru, a maa ṣeun, ifẹ ki iṣe ilara, ifẹ ki sọrọ igberaga ifẹ ki i gbero ohun buburu, a ma a farada ohun gbogbo." Nigbati enia kan mbọ wa si Ipinlẹ kan ti o sọ pe on ni ifẹ enia, ti awọn Ijọba Ipinlẹ na ti e ni on ni ifẹ sọ pe, ki oluwarẹ o maṣe wa ti o si nsare ṣe ofin! "Gbogbo e n i a ti laakaye wọn ba pe, y o bere pe, iru ifẹ wo niyi o?"

Ninu ọsẹ ti o kọja yi kanna ni awọn ọmọ ẹ g b ẹ ọdọ Dẹmọ tun nsọ ninu ẹrọ - asọrọmagbesi pe, Dokita Okpara ko gbọdọ ṣe ibẹwo wa si Ipinlẹ Iwọ O r u n Naijiria, nitoripe bi o ba wa, yio dabi igbati o "ntapa si ofin" Ijọba.

Awa oniwe Irohin Imọlẹ wa kesi ọga Agba awọn Ọlọpa Ọgbẹni Edet, pe ki o j ọ w ọ ki o da abo bo Dokita Okpara, lọwọ awọn ti nwọn le ma a gbero ibi si i, pe ki irinajo rẹ na o le yọri si rogbodiyan.
Dokita Okpara ti sọ pe, ofin ti Ijọba ṣe ko le da on duro, lati maṣe ipade ti on fẹ ṣe. Loni yi ni Dokita Okpara yio si bẹrẹ irinajo rẹ si Ipinlẹ yi. A si fẹ ki awọn Ọlọpa se idabo bo fun Dokita Okpara. 'Eegun ni on yio jo, ojo ni on yio rọ, alagba a ni on si fẹ woran"

Ṣugbọn ohun ti o ya gbogbo enia lẹnu ninu ọrọ yi ni wipe, iru asiko ti Dokita Okpara mbọ wa ṣe ibẹwo yi, kọ ni o yẹ ki Ọgbẹni (Oloye) T. O. S. Benson o lọ si idalẹ rara, o yẹ, o si tọ ki Oloye T. O S. Benson ti iṣe Igbakeji olori ẹgbẹ Alakukọ le wa lẹhin Dokita Okpara ninu irinajo rẹ. Bawo ni ibati dara to, ki Oloye Benson o wa nile ni ọjọ oni.

Ṣugbọn awa oniwe Irohin Imọlẹ lero pe, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti o wa nile ni yio gbaruku ti Dokita Okpara lẹhin ninu irinajo rẹ l o n i. Awọn agba ma a sọ pe, nitori were ita, ni ki i jẹki a le were ile jade. ni ọjọ ti were ita ba wọle, were ile ni a fi pade rẹ lọna. Nitorina, o yẹ ki Dokita Okpara o mu diẹ lọwọ ninu awọn "ẹhanna tabi janduku enia" nitoripe awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ le fẹ bẹ igi di oju ọna rẹ.

A lero pe, ẹnyin alaṣẹ Ijọba ko ni dakẹ ma a woran Ẹ maṣe dakẹ o.

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYE ẸKO

Olotu:- Yẹyẹnatu, Kilode, nwọn ni o nba ọkọ rẹ ja?

Yẹyẹnatu:- Ẹma da olori buruku rẹ lohun.

Olotu:- Olori buruku ni lo ti iru rẹ fẹ. Bo ba ṣe emi lo pe e bẹ ẹ ni, wa binu.

Yẹyẹnatu:- Bi ẹ ba ṣe iyawo yin bo ṣe nṣe mi, iyawo yin yio pe yin olori buruku kẹ

Olotu- O dara ki lo ṣe gan?

Yẹyẹntu:- ẹ gbọ nwọn ko fowo sowo oṣiṣẹ?

Olotu:- Nwọn fowo sowo oṣiṣẹ kẹ.

Yẹyẹnatu:- Olori buruku rẹ ni iro ni nwọn pa?

Olotu:-Ko jẹ sọ bẹ fun ọ kẹ

Yẹyẹnatu:- Mo tilẹ kọkọ gba a gbọ, ṣugbọn igbati mode ọja ti mo ni mo fẹ ra gari owo gari le, mo ni mo fẹ ra ẹran owo ẹran le.

Olotu;- Lootọ ni yẹn, gbogbo ọloja ti fi kun owo ọja

Yẹyẹnatu:- Hahẹn, Mo wa berẹ lọwọ wọn pe kilo de
Nwọn ni emi ko gbọ pe nwọn ti fi kun owo oṣiṣẹ ni, tabi emi ko si nilu

Olotu:- Ṣe o si sọ pe o wa ni lu

Yẹyẹnatu:- Ẹ jọwọ ẹ ma ṣe yẹyẹ rara, Njẹ bi on ba jẹ ọkọ ti nro rere pẹlu aya ko ni fi kun owo onjẹ

Olotu:- Ijọba ko sanwo fun

Yẹyẹntu:- Ijọba ko t i sanwo ni awọn ọloja mọ pe nwọn ti gba a tabi kini ẹ fẹ fi ye mi?

Olotu:- Ha, ijọba lo nda rudurudu yi silẹ Awọn ni nwọn jẹ ki ọloja fowo soja ki awọn oṣiṣẹ ko gba afi kun owo

Yẹyẹnatu:- Mo ti gba yin gbọ ju ki n s ọ p e ẹ npurọ lọ, Ṣugbọn se ko yẹ ki ọkọ mi fi kun owo onjẹ igbati gbogbo nkan t i l e owo?

Olotu:- Oye lootọ, ṣugbọn owo ti ko ba si jẹdi jẹdi ko le gba

Yẹyẹnatu:- O dara, ki ẹ mark ohunti ẹ sọ yen nitori bi ẹ ba dele wa nkọ ni fun yin lomi

Olotu:- Ha-ha-ha Ọlọrun ti conquer iyẹn Monlọ si Ibadan lọ pade Ọpara nitori irohin ko ni to afojuba

Yẹyẹnatu:- Hahen, ṣebi nwọn ni Akintọla ni ko gbọdọ wa

Olotu:- Akintọla ko ni ko ma wa, o ni ẹnikẹni ko gbọdọ to pade rẹ ni

Yẹyẹnatu:- Ṣe nitori irẹpọ Naijira ni yẹn ?

Olotu:- Yes kẹ nitori irẹpo Iwọ Orun ni kẹ

Yẹyẹnatu:- Kara ẹ ye puro funra yin sebi a o NCNC ati AG n f ẹ Ọpara bawo ni awọn wọnyi ṣe le rẹpọ pẹlu ẹgbẹ Akintọla nigbati o nṣe wọn nibi ?

Olotu Ibi wo? O ni ki ẹnikẹni ma ṣe ipade o tan. Hẹn ki nwọn ṣe l ẹ b i on na ba, ẹ lọ si ipinle Ọpara

Yẹyẹnatu Akintọla ko le lọ si ibomiran ẹgbẹ t i r ẹ ẹgbẹ awọn ọmọ Yoruba ti nfi ilu ṣiṣe jẹun ni ki ṣe ẹgbẹ anybody Ibọ ko l e e ṣugbọn Hausa miran le ṣe o

Olotu:- O jẹ ṣọra re

Yẹyẹnatu:- Nitori kini? Ẹbọ nle ko ju iku, karakira ko ju ọdọ Osagie kẹ ka bosibosi Olodumare ti ni bo ba kan bẹ ẹni gbero rẹ yio ba lọ

Olotu:- Ha, iyẹn le ju

Yẹyẹnatu:- Igbati nko ni ro ibi si wọn

Olotu:- Ha, jẹ ki nma a lọ bo ba da bẹ

Yẹyẹnatu:- Hẹn, o dabọ

---


## CLASSIFIED ADVT.

'KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812 HONG KONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

# IWE SI OLOTU

## A Nfẹ Ọrọ Ọlọrun Ninu Irohin Imọlẹ

E dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti njade lọjumọ lati kesi awọn onimọ ijinlẹ ninu Bibeli Mimọ lati le mọ fi ọrọ Ọlọrun gba wa ni iyanju ninu iwe Irohin Imọlẹ nyin nitoripe ọrọ Ọlọrun ni iye lori ju ohun gbogbo lọ.

Ko yẹ ki a gbagbe lati mọ ṣe ayewo ọrọ Ọlọrun o yẹ ki a ma mura fun ile wa lọrun ile aiye afọwọba fi silẹ ni atipe ofo ni gbogbo rẹ jẹ Ọrọ mimọ Ọlọrun sọ ninu iwe Oniwasu pe asan ninu asan gbogbo rẹ asan ni.

Nitori idi eyi ko yẹ ki ẹ wa aiye mọ aiya, Yoruba ni ẹ ba tuka l'ọja ẹ sọ di ilẹ ẹ sọ di ilẹ ẹ sọ ile aye di awailọ bi a bi fọkan si aiye yi ti nlọ ao ri wipe ọrọ Ọlọrun lẹ sẹ lai aiye ti awa yi o ṣọ ninu Mattew ori kẹrinlelogun n i p a idagiri ati irọkẹkẹ ogun ati bẹẹbẹ lọ.

Ọlọrun ko ma ba gbogbo wa gbe lailai amin.

Ẹ ṣe pupọ Olotu ọkọ Oba ko ni ṣa nyin lẹẹ.

Emi ni
J. A. Afọlabi
IGBAJA.

## Itan Yi Wa!

Awọn Yoruba lonpa lowe wipe aṣẹ iru eyi nbẹ ni ẹwa naọpe ko si nkan, olotu nibo ni eti fi itan yi si ti ẹ wa fun wa ni awọn ẹsibiti itan kan, to gbamuṣe to fun wa ni atata ijinlẹ Yoruba, gbogbo awọn ọmọ Yoruba ni o ni ẹtọ ati ma ka itan yi.



J. O Shoyinka

Itan yi je itan ti enia nl lati r o nu jinle daada bi enia ba nka itan na nṣe ni ọgbọn ati oye yio ma ko si enia lori ti okan oluwre yio si bale ti inu enitl nka yio si ma dun bi inu ole to gbe ọke iyere to y bi ọkẹ owo ni on ri gbe.

Mo gbadun itan na emi ati awọn idile mi ni a njumọ ka, mo tun nfun awọn ọrẹ mi ka, Iwe orin awọn oni gbogbọ lo si wipe "Enitl o ba tọ oyin wo ki ofun enikejirẹ Oluwa korira anikanjogbọn.

Awọn ọrẹ mi ti o nka itan na dupẹ lọwọ mi inu nwọn si dun gidigidi to jẹ wipe nwọn ko duro de ti emi mọ, ti ara wọn ni nwọn nran ọkan ninu wọn sọ fun mi pe, gbadun koran iba rara.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Ẹniọla
Ogbomọsho

## Ẹfufulẹlẹ Nkọ?

Ẹ dakun ẹ gba mi ni laye diẹ ninu iwe nyin alaka kọgbọn ati oye lati dupẹ pupọ lọwọ ọlọla wa Efufulẹlẹ ti nsiwa lati mpa iwa ibajẹ ti o wa ninu aiye wa yi ati ọna ti a le fi kapa rẹ,

O to ọjọ melo kan ti a ti gburo ọlọla wa na kẹhin iuu mi yio dun pupọ bi ọlọla na ba tun le mọ ba awọn ọrọ rẹ lọ.

Bẹna ni a fun ngbadun awọn Alhaji Y. Disu, Arẹmu Erin, Ẹrukobodo ati alejo J. Ọla, Wins o ti to ọjọ mẹfa ti ọlọla wa na ti kan si wa a nreti rẹ ninu osu yi.

Mo ni lati dupẹ nla lọwọ ọlọla Ejongboro fun awọn irohin aladun ti o nmọ kọ sinu iwe irohin Imọlẹ ti a ngbadun ni gba gbogbo Ẹ ku iṣẹ o ajinde ara yio mọ jẹ o.

Mo dupẹ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
JIMOH ELEMỌ
Eko

## Ijọba Eko E Fi Eyi Ṣ'ero

Inu mi yio dun pupọ bi ẹba le gba mi ni aye ni u iwe Irohin Imọlẹ alaka gbadun ati aka kọgbọn lati kesi Ijọba Ibilẹ Eko paapa Apapọ Ijọba lati ba wa moju to nkan ti ole ba alafia ilu wa jẹ tabi ti o le jẹ ki ada nu ati ijauba wọ ilu Eko igi gangauran mọmọ gun mi loju o okere ni ati sọ.

Asiko to ti oyẹ ki Ijọba se ofin ti ko ni fun awọn ti nta epo pẹtiro (petrol) ni abẹ buka ni aṣẹ lati ma ta mọ, a fi awọn ti oba kole fun ni o tọ to si yẹ ki nwọn fun ni aṣẹ ati ma to.

Kakiri agbegbe Eko ni nwọn gbe ada iru aṣa yi nani Mushin Yaba, Ebute-Metta ati Apapa akoko to fun awọn enia wọnyi epo pẹtiro.

Ọlọrun maje ki a sofo emi o aṣẹ sugbọn o g u n agbọtẹlẹ ki to ato os

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
L. B. Akinọla
Eko

## Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti a si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Erok wa si ile itaja wa ni Nọmba11, Ishiba Street Odo

## Apejuwe Ile Iṣẹ Wa

Ẹ wọ Bọọsi ti o nlọsi Lawanson ni Yab 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adiresi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igb Arun | |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 20/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 25/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 5/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Ṣiṣe | 20/- |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba eti psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6d |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egobgi awọn Faranse gidi ti a pe'ni:

**'CORSIVER'S**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atanatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹra ̀u tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu ... lere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street; Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STOE
Tinubu Square Lagos.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Obinrin Ti Ko Bi Ọmọ Bi

Ni asiko kan nigba lai lai obinrin kan wa ti orukọ rẹ njẹ Ọlọrunlowu obinrin yi ko ri ọmọ bi lati igbati o ti de ile ọkọ. Obinrin yi jewe, egbo sibẹsibẹ ko ri ọmọ na bi, eleyi si jẹ ibanujẹ ọkan rẹ pupọ to bẹ ti ofi jẹ wipe ko si ọjọ ti ọkan rẹ ki gbọọgbẹ, ti yio si ma sọkun

Gbogbo awọn ọdọmọbinrin ti nwọn si tun wọ ile ọkọ lẹhin tirẹ, gbogbo wọn ni Ọlọrun yọnda ọmọ fun.

Nigbati obinrin yi ba ro gbogbo eleyi, inu rẹ asi bajẹ gidigidi şugbọn obinrin yi a wa ma ranti orukọ ara rẹ yi pe Ọlọrunlowu, nitoripe ọkọ on njẹ on lẹri pe kise wipe on fi ara on şere lati arọ ọjọ wa ni bikoşepe ayanmọ ti Ọlọrun fun on ni eleyi, onsi gbọdọ gba ni, ati wipe gbogbo awọn ti Ọlọrun npese ọmọ fun, ki işe mimọşe wọn lotobẹ.

Nwọnyi ni iwasu ti obinrin yi ima fun ara rẹ nigbati o ba ro gbogbo ọrọ ara rẹ ti o si sun Boya nitori airi ọmọ bi yi ni obinin yi fi nmọ nhu iwa rere si gbogbo awọn aladugbo rẹ. bi o si jẹwipe iwa ti Ọlọrun fi jinki rẹ lati ode ọrun wa ni, ẹnikan ko le sọ, şugbọn nipasẹ iwa rẹ yi, obinrin yi ri eju rere Ọlọrun nigbati o di ọmọ ogoji ọdun, osi bi ọmọkunrin kan, latipasẹ kiloli kan.

Lẹhin igbati Obinrin yi bimọ tan, inu rẹ dun pupọ ti ko şe l'ẹnu sọ. Osi ndupẹ lọdọ Ọlọrun fun işẹ ribiribi ti Ọlọrun ti şe fun ati wipe on bọ lọwọ ebu ati orin owe ti awọn orogun on ma nkọ bu on.

Lati igbati Obinrin yi ti bimọ tan ni inu awọn orogun rẹ ko dun mọ, ti nwọn si fi ẹsẹ le ọna ile ologun lati ripe nwọn pa ọmọ.

Gẹgẹbi atişe mọ wipe Obinrin meji ni ọkọ wọn ni atipe on nani oşikeji bẹni iyawo Ọlọrunlowu yi nsare sihin sare sọhun lati ri ẹbin ọmọ Ọlọrunlowu şugbọn iparẹ ko ka ọmọ na titi ọmọ na fi to ilelọ, pẹlu awọn ọmọ onna.

Bẹni ọmọ iyale ti o jẹ ọmọ'ẹhin awọn yo kusi mọwe ju awọn ọmọ iyawo lọ, gbogbo igbati awọn ba ti şe idanwo ni ile iwe ni awọn ọmọ iyawo nma feli ti ọmọ iyale ti o jẹ ẹyọ kan şoşo si pasi.

Eleyi tun jẹ ibanujẹ fun iyawo ti o si tun nwa ọna lati pa ọmọ iyale.


# MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise MODUPE PRESS Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs*

Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.


## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 19) Iwọ mura lati ba ọrẹ rẹ se nkan iwọ yio si ri ere nla jẹ ti ẹnu ko le sọ okiki rẹ yio si kan larin ẹgbẹ ni irọlẹ oni.

PISCES (Feb 20 Mar 20) Gbẹkẹlẹ rẹ le alabasişẹ ni owurọ yi bi o ba di ni ọsan, iwọ yio ri ẹlomiran.

ARIES (Mar 21-April 20) Inawo nla rẹpẹtẹ kan yio şẹlẹ si ọ ni owurọ oni şugbọn ki o mọ pe owo ti o ba na yio mu ere pupọ wale.

TAURUS (April 21-May 22) Şọ owo na ki o ma ba lo gbese nitori ọrọ nawo-nawo ni awọn ma gbe ko ọ, ọgbọn ori rẹ ni ki o ma lo.

GEMIMI (May 23 June 21) Işẹ ti o ma şe ninu eyiti iwọ yio ri ere pupọ jẹ, işẹ na yio tẹ ọ lọwọ laipẹ.

CANCER (June 22-July 22) Alafia yio to gbogbo awọn ara ati ẹbi rẹ ọkan ninu awọn toju ọ lọ yio se ohun ti o fẹ fun ọ.

LEO (July 23 Aug 23) Ohun ti o dara ni ki o lọ ra Ọja ni ita iwọ yio si ba ire pade ni ọjọ toni.

VIRGO (Aug 24-Sept 22) Lo egbogi rẹ loni ki o ba le ri ona igbagba lọsan iwọ yio ba ire pade.

LIBIRA (Sept 23-Oct 22) O dara ki o lọ ra nkan ti o ba fẹ ra ki Ọsan to kan iwọ yio si gbalejo ni ọsan

SCORPIO (Oct 23-Nov 22) Iwọ irohin kan yio tẹ irohin jade ni eyiti iwọ yio jere rẹpẹtẹ.

SAGITTARIUS (Nov 22-Dec 22) Owo yio ma dun lọwọ rẹ ki ọsan to pọn şe suru, ki o san gbese fun ọrẹ rẹ kan.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 20) Işẹ rẹ yio ma lọ rege rege fun ọpọlọpọ asiko ko da bi oba fẹ li ẹ ye na silẹ fun ẹniti oju o lọ.


# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹn fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe Ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ ototo, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile, Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Ọj. Lagos Nigeria
8, Palmchurch Street, Ita Faji)


## E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojoojumọ Ki ẹ Si Ma Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

### ỌJỌ AJE MAY 1 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege |
| ABEOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode Igbo-Ọra |
| IJEBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| IJESHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| EGBADO | Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

### ỌJỌ IṢẸGUN MAY 2 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ, | Oyingbo Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagb Ogunjana, Molete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosn, Og:re Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| JẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi Ile |
| ẸGBADO | wlagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Su-Aa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

### ỌJỌ'RU MAY 3 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

### ỌJỌ ỌJỌBỌ MAY 4 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu, Mamu |
| JẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

### ỌJỌ ẸTI MAY 5 FRIDAY

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

### ỌJỌ ABAMẸTA MAY 6 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Berẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Remọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

### ỌJỌ AIKU MAY 7 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹ Babalokuta, -Ijaiye Orile. |
| IJẸBU | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. Aiyetoro, Ado-Oda. |
| ẸGBADO | |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

### ỌJỌ AJE JUNE 8 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagrey |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Okun-Ọwa Eruwe Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati ọwọ EJON'GBORO

### SURULERE

Awọn ọlọpa ti mu ọdaran kan nitoripe o lọ dena de Ọgbẹni O u Eraig o si tun fi ipa gba pọnnu mẹwa (£10) ti owa ninu apo Olu.

### SYDNEY

Enia mẹdọgbọn lo fi ara pa ti mọto mẹta si jona si nu ile nigbati ijamba ina nla ṣẹlẹ larin ilu ninu ọsu ti o koja yi.

### SAN-FRANCISCO

Gbogbo ilu gbojikan fun ariwo nigbati awọn enia mẹfa kan fi ina ṣere ti ina si jo awọn mẹfẹfa pa sinuile

### EKO

Ariwo nla ta gee, nigbati ọmọ ile iwe kan Ọlashupọ ti ongbe 2 Bajulaiye Str Ọtta re kọja oju titi ni Idumọta ti osi sure ko si ẹnu mọto ọmọ na ku bambam mọto na ko duro awọn Ọlọpa ti berẹ si wa oni moto na

### IBADAN

Oloye S.L.Akintọla alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwo Orun ti sọ pe Ijọba on yio bẹrẹ si ma da s rin ti o ba tọsi iwe irohin to ba nkọ irohin ti ko da si Ijọba on.

### ABIRIBA

Awọn ọlọpa bẹrẹsi wa Ọkunrin ti o pa awọn meji kan nibiti nwọn gbe nsere ti o si pa awọn ọmọ mejeji ni ojo kanna wọn ti gbe oku awọn ọmọ mejeji lọ ile iwo san.

### ỌBALENDE

Gbogbo ero lo parojọ si eti odo ọsa nigbati awọn ọlọpa ri oku ọmọ titun kan, ninu odo ọsa ti oku ọmọ na ti wu ti o si bẹ ṣugbọn awọn ọlọpa gbe oku ọmọ na lọ si ile wosan

### EKO

Odaran kan ti o lọ sinu ile itaja awọn oyinbo oni ṣowo oyinbo U. T. C. ti o si lọ ji ọṣẹ "Asepso" meji ti iye owo rẹ jẹ (3/6) ni awọn ọlọpa ti mu.

### MAKOKO

Ni ọjọ aba mẹtatiiṣẹ gbọn ọjọ oṣu ni awọn ọlọpa ri ọdọọmọbinrin kan, Fade-rera mọ gbe yiwa ti o ngbe 33, Ramọtu Street, ti o jasi oju odo ọsa nwọn ti gbe oku ọmọ na

# IROHIN IMOLE

MỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

708 MONDAY, JUNE 1, 1964 (2D)


## Ẹniti Iyawo Rẹ Kọsilẹ Bẹ Si Kanga !

MAIDUGURI:— Gbogbo awọn ero kotu lo rẹrin arintakiti nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan Y. Shuwa, ti o nṣlọ agba wa siwaju adajọ fun ẹsun pe o fẹ pa ara rẹ ti o si sọ sako fun ile ẹjọ pe, "o tẹ mi lọrun ti mo ba ku ju wipe, ki nya oju mi silẹ ki iyawo mi ma a ba ọkunrin miran lọ lọ"ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọgbọjọ oṣu ti o kọja yi

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, awọn ara ile Ọdaran na ni nwọn lọ ṣe ofofo fun un wipe, iyawo rẹ Iyaafin Ya Fanne Shuwa fẹ kọ ọ silẹ, o si ti nko ẹru rẹ jade nile.

Ọlọpa na ni bi Ọdaran na ti gbọ ọrọ yi lo ba sare dide ninu ile ti o si lọ bẹ sinu kanga ti o wa larin ita ninu ile wọn.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ara ile ba sare jade ti nwọn si sare yọ jade.

Lojukanna ni nwọn ba gbe lọ si ile iwosan fun itoju nitoripe o farapa pupọ o si ti tun mu omi ki nwọn to sare yọ ọ jade.

Nigbati Ọlọpa na se alaye tan, ni adajọ wa bi ọdaran na lere pe, "kini se ti o fi ko sinu Kanga?" ọdaran na ni "Ẹ jọwọ, mo fẹ iyawo mi, nko le jẹ, nko si le mu laiko ri iyawo mi."

Gbogbo awọn ero kotu lo ku ṣẹrin nigbati ọkunrin na sọ bayi, adajọ yẹ ẹjọ na si ọsẹ ti mbọ.

# AWỌN ONIJIBITI MEJI WẸWỌN ỌDUN MẸJỌ

ONITSHA:— Ọgbẹni B. C. Nwosu, adajọ agba Ile-ẹjọ kekere Onitsha ṣe idajọ pe ki awọn Ọdaran Ọrẹ Onijibiti meji kan, Nonyelu Oyeagba ati Felix Ofogbohvere lọ si ẹwọn Ọdun mẹjọ nitoripe, nwọn jẹbi ẹsun wayo, jibiti, ilefifọ ati ole jija ti awọn Ọlọpa fi sun wọn ni Ọjọ Aje ti iṣe Ọjọ kẹdọgbọn Oṣu yi

Iyaafin Cecilia Nwanko ti o ba awọn Ọdaran Ọrẹ mejeji ṣẹjọ ṣe alaye pe, on ti mọ awọn Ọrẹ mejeji na ti pe, atipe iṣe onisowo ni awọn mejeji nṣe.

Iyaafin Cecilia tun ṣe alaye pe ni Ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji Oṣu yi, ni awọn Ọdaran mejeji na wọle wa ba on nibiti on ti ntọju Ọmọ on ti ararẹ kọ ya.

Nigbati awọn Ọdaran na wọle wa ti nwọn ba Ọmọ na lọwọ on ti on nṣe itọju Ọmọ na, ni nwọn ba sọ fun on pe, ki on tete yara lọ ra, oogun kan ni ṣọbu, ki on si maa lọ Oogun na fun Ọmọ on.

Lẹsẹkẹsẹ ni on ba sare jade ti on si lọ ra Oogun na ni ṣọbu ki on le lo fun Ọmọ on na, ṣugbọn nigbati on yio fi de, awọn Ọdaran Ọrẹ mejeji ti palẹ gbogbo ẹru on mọ nile, ti nwọn si kọ gbogbo rẹ lọ.

Lojukanna ni on ba gbe ọmọ on pọn ti on si lọ fi ọran na han awọn ọlọpa ni taṣan lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa ragabu awọn ọdaran ọrẹ mejeji

Ninu ẹjọ ti awọn ọdaran mejeji na ro niwaju adajọ lati fi gba ara wọn kalẹ, nwọn ni awọn ko lọ ko ẹru obirin, na oju lo nkan awọn ti ko jẹki awọn duro de obinrin na ki o fi de ba awọn ninu ile.

Awọn ọkunrin na tun sọ siwaju ninu ẹjọ awijare wọn pe, gbogbo ẹru obirin na lo wa ninu ile rẹ ki awọn to jade, bọya nigbati awọn jade ni awọn ole miran wọ le ti nwọn si lọ ko ẹru rẹ.

Ninu idajọ re, adajọ agba Ọgbẹni B. C. Nwosu ṣe alaye fun gbogbo awọn ọdọmọde ti nwọn nfẹ la ọla ojọ pe ki gbogbo wọn lọ wa iṣẹ ṣe, ki nwọn si ye ma a wo nkan-oni-nkan.

Lẹhinna ni o wa paṣẹ pe ki awọn Ọdaran na lọ si ẹwọn ọdun mẹrin-mẹrin, ki nwọn si lọ wa iṣẹ atata kan ṣe ti nwọn ba ti jade.


THE ANSWER TO

TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED

AFTER SALES

SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.